# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. III. No. 108. SATURDAY, AUG. 9, 1924. Fourpence.



## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods,*

**"Specialities: Enamelware Beer. Wine. Iron Bedsteads. Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds. Clay and Briar Pipes, Champagne. Cement. Biscuits in cases. Gun Powder. Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice. Accordeons, Piano. Padlocks. Beads. etc., etc., etc."**

---

CHIEF SECRETARY'S OFFICE 12 AUG. 1924 LAGOS

**N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.**

OYINBO ***J. F. SICK***

Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, orișirișị Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita :—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Wajì, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elẹjo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Òlokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹkẹ didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumâdan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa ; A ni nkan wọnyi fun tita :—

Ikoko taba Onigi, Jigi, Așọ Aran, Ẹrọ agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Ajàrà (*Wine*), Awọn onjẹ Ipanu, așọ iș'ọșọ, Ẹrọ ere ọmọde, Ohun Ọșọ, Àbẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Mașini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile owo ni :—Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

# John Walkden & Co. Ltd.

SUNDRIES DEPT.

MARINA, LAGOS.

## We recommend you to try our :—

"Elephant" Beer

Ginger Ale

Lemonade

Red Buffalo Gin

Black Prince Gin

Gilbeys Gin

Old Tom Gin

## QUALITY THE BEST.

ALL PRICES REDUCED.

we hold a large stock of various Sundry Goods at cheap prices.

*Editor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Offices :* 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

—:o:—

BẸNI TIRẸ RI LAWYER "OBI" DA-NSAKI.

A Ṣ'ỌMỌDE ṢEBI AGBALAGBA.

Ijo Ilẹ wa ti a gbọ pe awọn Ẹgbẹ Ọmọdemọṣọ wa jo ni alẹ *Friday* ọsẹ tokọja ni 'le Afari-Ogun l'ẹhingbẹti nigbati awọn Ẹgbẹ Ododo *Nigeria (Union of Young Nigerians)* na ṣe ariya kan lalẹ ọjọ yi wu ni lori pupọ ; a tilẹ gbọ pe diẹ ninu awọn Oloye wa bi Olorogun, Oluwa, ati Eletu wa yẹ ariya na si nipa wiwa sibẹ.

A dupẹ lọwọ Ọgbeni wa *Lawyer* Ayọdele Williams ti gbogbo Eko mọ bi *Lawyer* Obi (ọmọ ologbe Bọkunni Obadiah Hutchinson Williams, oninure ti 69, Ita *Victoria* l'Eko nibi sa niṣe,) fun ayan rẹ lori Ẹgbẹ ti nwọn da silẹ yi fun agbajọ pọ awọn Ọdọ wa, lati ma ṣe iṣẹ ẹyẹ ni 'lu, ohun ti o dun ni nibẹ ni pe a gbọ pe nigbati Ilu Apọnran nro kikan ti Batakoto si nsọ t'ẹnu rẹ ti awọn kokoro si nfi ẹsẹ ra ijo ilẹ wa na niti oloyinmọmọ, bẹ ni ọga Oyinbo Ọlọpa Alatojubọ kan yọ de ganran ti o wa pakuta si i pe ki nwọn da ijo na duro nitoripe Iwe Ilu ni wọn gba ; eyini ni pe bi nwọn ko ba le ma ba ijo Oyinbo "Alasẹ-mọ p'onjo" wọn lọ, ki nwọn da ilu Apọnran na duro ; a si gbọ pe *Lawyer* adara bi ẹrin yi sọ asọye alamọri ohun ti o njẹ Ilu lorisirisi ọna fun Oyinbo na, ṣugbọn pabo ni. O si la ye Oyinbo na pe gẹgẹbi awọn ara *Scotland* ni Oke Ilu Oyinbo ti nfi Ilu wọn jo ijo tiwọn, ti awọn ara *Ireland* si nṣe bẹ pẹlu, bakanna ni awa Yoruba ni lati fi Ilu tiwa jo tiwa ; ṣugbọn Oyinbo yi kọ jalẹ lati jẹki nwọn ma ba ijo na lọ ; bayi ni o ṣe agboran s'eṣu, to ṣe eti gbọyin s'ẹbọ.

A dupẹ pe *Lawyer* na ni on ki yio sinmi titi on o fi ṣe atunṣe na. Ẹnyin ara, ẹ ko wa ri pe pupọ ninu ẹnyin ti ẹ ti nfi ijo wa da agunla, aguntẹtẹ ri, ti ẹ si ngbọn papa mọ ijo-onijo, ijo Alasẹ-mọ p'onjo, ijo Oyinbo, ijo *Ball*, lo mu esekoyi ana wa bayi ?

A fẹ ki irufẹ awọn ti nwọn ma nfi ọwọ rọ ijo wa sẹhin lọna yi ronu, ki a si ran *Lawyer* Ayọdele Williams lọwọ lati jẹki awọn Oyinbo mọ pe, bi o ti wa l'Ake bẹ lo wa l'Oko, eyini nipe bi awọn ti ni Ilu ati Ijo tiwọn bẹ si ni awa na ni tiwa pẹlu.

Talo ma wipe Ilu ati Ijo awa Yoruba ko "mijọriti" ngbọ, Abẹkẹ, Idowu, Abẹbi Adukẹ ? Nigbati o ba nf'ẹsẹ ra a l'agbo, ti awọn *Boys* ba si nda oporo owo bo ọ nipa yiyẹ ọ si nikankojọkan, igbadun rẹ nkọ o ẹnikeji, ko ha bu-aya bẹ ; wọin ! Ẹ ma da yẹyẹ lohun !!!

T' OWO LAWI, TA LO' NDA HỌ OWO ?

Isinmi ti Ile Owo gba ni *Monday* ọsẹ yi fun ọgọrọ awọn Onisẹ Ọba ati awọn Onisowo laye "na iyẹ sa" Ariya ti awọn Onisẹ Ile-Owo Nla (*B.B.W.A*) ti ilẹ yi, pẹlu awọn Onisowo-Ọkọ A-f'ele-rin ṣe ni Ebute Mẹta gb'ọwọ ; yungba-yungba ni gbogbo ere ọjọ na ndun bi agbayun.

Boya pupọ ninu awọn ọkawe wa ko ni mọ pe ọjọ ti Ọgbẹni kan ti a npe ni Paterson ara *Scotland* ni Oke Ilu Gẹsi da Ile-Owo Nla ti England (*The Bank of England*) silẹ ni ayajọ *Monday* tokọja yi ; nitorina ni a ṣe ya ọjọ na sọtọ fun iranti Ọdun *1694* ti Ọgbẹni na da *Bank* nla na silẹ ; iyẹn di ọgbọn-le-ru-gba ọdun nisisiyi (*230 years*) o je igba aiye awọn Ọba Ilu Gẹsi ti a npe ni William ati May ki awọn ọkawe wa ja wa, ti a ba fi eyi ṣe

ete lẹṣọ ni, ṣugbọn ta lo le sọ igbati a da ẹka *Bank* Nla (*B.B.W.A.*) tibi silẹ? Eyini ni *Bank* ti ọmọ Mammy "G.P." ti Ọgbẹni E.A.T.A.J. Ajitẹdidun ni-duru ko kẹrẹ ni dida silẹ pẹlu awọn ara wa, bi Ọgbẹni Ọlọla J. J. Thomas ati awọn Oyinbo G. W. Neville ati Sir Alfred Jones? Ọdun *1894* ni, o nlọ si ọgbọn ọdun nisisiyi.

Gasa, ọjọ nlọ a ntọ ọ.

### OKUTỌ ẸKIMOGUN ARA IJAMỌ, OSUAN SUAN Ṣ'ỌKỌ FỌLAṢADE.

A gbọ pe Ọgbẹni C. Ibarẹ Akinsan, Akọwe Agba ni'le Ọba l'ọdan ni 'lẹ yi gba isinmi oṣu mẹta ninu iṣẹ rẹ nilọlọyi; nigbati ẹ ba fi ọkan gbe pe ọdunni lo di ọdun kejila ti o ti gba iru isinmi yi kẹhin, Ẹ ko ni ṣai ri pe ọkunrin ta fi ṣepe ọkuntin ni, ninu akikanju iṣẹ ṣiṣẹ.

A sọpe oko ni Ọgbẹni na ma fara si ju ni gbogbo akoko yi; o dabi ọrẹ wa yi ti mọ igbadun to wa l'oko nipa pipinnu ati lọ sinmi nibẹ.

Ẹ gbọ bi Aribiloṣo ti sọrọ igbadun ibẹ si :—

"Ko s'ohun to dun bi Oko,
Oko d'adun ju,
Igb' o ba jiyan tan wa wọ gẹrẹ
Wa f'ẹhin ti,
Wa m'ago taba wa sọ kẹkẹ
Wa d'ọrọ nu."

### BISHOP IṢỌLA ṢE OHUN ARA LALẸ IJỌUN !!!

Didun ranyin ranyin bi oyin ni orin ti *Bishop* Adedeji Iṣọla Olulana Ijọ *Brotherhood* nibi ṣe, ti o si kọ fun ni ninu Isin alẹ *Sunday* to kọja ni Ilupesi, fun lile arun to sọ'lẹ s'Ebute Awo laipẹ yi lọ bambam. A yọda tunni lati tẹ orin na pẹlu akanṣe Adura ti *Bishop* na ṣe sinu "Eko Akete" ti ọsẹ yi nitori Aluba yi, fun anfani awọn ọrẹ wa aimọye ti ongbẹ ati ni orin ati adura na ni arọwọto, ti ngbẹ lati ijeje wa.

### EPE ILA KI M' AGBỌNRIN, EWỌ

A fẹ ki ẹsọ ki o to awọn Gambari to wa ni Oko-Awo nisinsinyi, fun Adura iku ati epe ṣọrọṣọ ti nwọn ntọrọ fun Ọgbẹni Mọmọ to wa ni *No. 71* Ita Alagba fun riro ti awọn afọ'nu-fọ'ra Gambari nwọnyi ro pe Ọgbẹni Mọmọ yi lo ṣe okunfa awọn Ijọba wa s'Oko Awo nigbati arun Ajinipa-bi-idan na bẹ silẹ nibẹ; awọn Gambari yi ko ha mọ pe awọn ẹnikan to njẹ Aruna Gana ati Gbadamọsi lo bẹ Ọgbẹni Mọmọ ni ipari oṣu tokọja lati lọ ba wọn gba Iwe-Oku fun sisin ẹgbẹ wọn kan ti o ku ti a npe ni Ishaka Dansokoto ẹniti a gbọ pe inu-ṣiṣu lo ṣe oniko rẹ lọ s'ode ọrun a si gbọ pe nigbati a sọrọ yi fun Ọga Ile Agba-iwe-Oku l'ẹhingbẹti, lẹhin igbati o ti bere ọrọ diẹ lọwọ awọn enia wọnyi tan pẹlu Mọmọ, ti Mọmọ si fun u ni esi ti o tọ, Ọgbẹni na fun Mọmọ ni iwe kan fun Ọgba Awọn Dokita Ọba; lẹhin eyi, nṣe ni Aruna Gana ati? Gbadamọsi ti Mọmọ sin lọ na salọ bambam. Ẹ ko wa ri bi Gbaranmi ti ndi ẹlẹru bayi Agbare-gbabọ rẹ nipe a ni lati "Jury" oku Ishaka Dansokoto na nigbẹhingbẹhin; kilo ha kan ti Mọmọ ti o ṣe iranlọwọ sisin wọn lọ gba iwe, ki o to di ogun pe awọn Gambari Oko-Awo ntọrọ Adura iku fun u?

Ẹnyin ab'aram'ore jẹ wọnyi, pẹlẹpẹlẹ o, bi bẹkọ tẹtẹ Ọba a jẹ nyin!

### IYA L' ỌJA, Ẹ MAKU ETUTU ỌJỌ !!! IMALE SỌRỌ OJO KUN, O NI ỌLỌRUN JẸRI ON: "TO MỌ NDALA" !!!

O dabi ẹnipe ọrọ pataki ti a kọ sinu Iwe Irohin wa ti ọsẹ tokọja niti "Bayi la nṣe ni'lu ẹni ewọ ibomiran" ka gbogbo awọn Oniṣowo obinrin Ita Faji lara bi aṣa imu; nitori ni *Thursday* (Alamisi) ọsẹ yi, ko si ẹnikan ti o pa'tẹ ninu wọn, nṣe ni gbogbo wọn nse ti nwọn nsọ lati arọ d'alẹ; ki aita Ọja wọn ti nwọn ti ngakiyesi l'ọjọ pupọ sẹhin yi ba le dawọduro; a si gbọ pe ko si ẹniti o gb'oju-gb'aiye gbe ọja wa ita ninu wọn lọjọ na, ti nwọn ko jẹ ọja na. Nitotọ agbajọ ọwọ la fi nsọ aiya—Ki Baba ma ṣai gba ajo awọn Iya wa wọnyi o. Aṣẹ.

## Ẹ KU EWU ỌKỌ.

Inu wa dun pupọ lati ki Mrs. G. H. Savage ẹniti o de ni *Tuesday* ọsẹ yi lati *Cape Coast* kabọ. Iya afin yi je iyawo Lọya G. H. Savage ti *Belvedere House, Cape Coast*, o si jẹ ọkan ninu arẹwa obinrin ọmọ ologbe Mr. ati Mrs. J. Blackall Benjamin ti Prospect House, Bishop Street, Lagos. Ko si ni'le nigbati baba rẹ ku, ati ẹgbọn rẹ Mrs. R. A. Wright ti Ijeun House, ati aburo rẹ Mrs. Layinka Agbebi, ẹniti o ṣe'ku ni iwọn oṣu kẹrin sẹhin.

Laipẹ yi ni ọmọ Mr. ati Mrs. G. H. Savage meji Percy ati Victor Savage gba oye *Bachelor of Art* ti *Durham University* ni Saro, adura wa si ni pe ki Ọlọrun ninu anu Rẹ lọra ẹmi awọn ọmọ rẹ na lati wulo fun ire ati ilọsiwaju Ilu wa gẹgẹ bi orilẹ-ede.

A ki gbogbo ẹbi l'ọtun, l'osi, a ki awọn Savage, a ki awọn Benjamin, a si ki awọn Bright. Ẹku afojuba.

---

## ORIN IṢỌLA OLULANA.

*Fun enia gbogbo, nitori Ajakalẹ Arun ti mbẹ l'ode Eko nisisiyi.*

### ARA-LILE L'OGUN ỌRỌ.

*Ohun Orin* :—"Wa bi titi wa bi Larinka etc."

1. Mimọ-toto ni Baba ma jẹ, } 2
   Ẹ jẹ ka ranti—
   T' ara-lile (2) ni ka ma du o,
   -(Ni ka ma du o)-
   T' ara-lile ni ka ma du o,
   T' ara-lile (2) ni ka ma du, t' ara-lile.

2. Finnifinni l'ara wa ma fẹ, } 2
   Ka ma ṣe riri—
   T' ara-lile ni ka ma du o, etc.

3. Ka "gbamuṣe" n'ti ka ma "dọti" } 2
   L' Ọlọrun wa fẹ—
   T' ara-lile ni ka ma du o, etc.

4. Ka gba' le mọ, k' Eku ma le wọ } 2
   Ni ka la mu gbọ—
   T' ara-lile ni ka ma du o, etc.

5. Ka gba'le tan, ka la gb' Ẹkule } 2
   N' Iṣẹ Afinju—
   T' ara-lile ni ka ma du o, etc.

6. Ka ga f'n Aja at' Ologinni } 2
   Tori Inọ sẹ—
   T' ara-lile ni ka ma du o, etc.

7. K' Inu ko mọ, k' Ara mọ pẹlu } 2
   Ka tun ṣe giri—
   T' ara-lile ni ka ma du o, etc.

8. B' Inu ba mọ, Ara o rọ wa } 2
   A o ṣe "gbẹdẹ"—
   T' Ara-lile (2) ni ka ma du o,
   -(Ni ka ma du o)-
   T' ara-lile ni ka ma du o,
   T' ara-lile (2) ni ko ma du, t' ara-lile.

Aṣẹ.

---

Adura Iṣọla, Olulana, fun Enia gbogbo, nitori Ajakalẹ Arun ti mbẹ l'ode Eko nisisiyi.

Amodi ki iṣe Ọlọrun, Ọmọ Ọlọrun l'emi...... (Lagbaja) Amodi ode yi ko ni d'ọdọ mi, "Ko ba wọn wa ki nba wọn lọ." Amin.

## AKIYESI.

Ẹ gbiyanju lati ma kọ Orin yi *mgba-gbogbo*, ki ẹ si ma gba adura yi *lọkanlọkan* lẹhin ajo nyin ati Ikilọ gbogbo miran ti ẹ ntẹle nitori ki ẹ ba le bọ lọwọ Ajakale Arun yi, nitoripe, asẹhinwa-asẹhinbọ, "*Ọkan ẹni l'Alufa ẹni*." Ẹ ma ranti nigbagbogbo pe, ẹnikẹni ti *Ọkan* rẹ ba ti gbabọde lọwọ Ẹru, Aisan, tabi Iku, ko tun si ajo, Imọran tabi iranlọwọ miran mọ to le ṣe oluwarẹ l'ore ninu Aisan tabi Iponju rẹ. Nitorina, adura atọkanwa mi ni pe, ki a maṣe ri ẹnikẹni ninu wa ti *Ọkan* rẹ yio gbabọde Ẹru Aisan tabi Iku lọwọ Ajakalẹ Arun ti mbẹ l'ode Eko nisisiyi.

Amin.

A. ADEDEJI IṢỌLA,
*Olulana ati Onihinrere.*

---

## Thanks for Sympathy.

Mr J. Ọlatunji Vincent of Elegbede Villa, 15, Oke-arin Street, Lagos hereby returns his sincere thanks to all those, who by personal calls, letters and otherwise, have expressed sympathy with him on the occasion of the death of his mother at the above address, on the 27th *ultimo*.

---

## A DUPẸ ỌJỌ.

Ẹni-ọwọ J. E. George ati arakunrin rẹ, Ọgbẹni J. S. George, fun ara wọn ati fun awọn ẹbi wọn 'yoku, ṣe ọpẹ lọpọlọpọ l'ọwọ awọn ogunlogọ ọrẹ l'oko, l'odo, ti nwọn ba wọn kẹdun ni orişirişi ọna nigbati Iya wọn olufẹ ṣe alaisi ni ọjọ kejile-logun oṣu July ti o kọja, ni 'Ebenezer House,' Imọ, Iṣabo, Abẹokuta.

**EKO AKETE.**

EKÓ, SATURDAY, AUGUST 9, 1924.

## Ẹ ṢEUN ṢEUN, ỌMỌ AFINJU ỌLỌJA TO S'ỌYỌ RO.

Kugu ni Ipade Ẹye ti awọn Ẹgbẹ Ọmọ Yoruba to mbẹ ni'le yi ṣe fun Ọgbẹni Ẹni-Ọla E. H. Oke ni aṣalẹ *Wednesday* Alaruba ọsẹ yi ni'le Afari Ogun l'ẹhingbẹti nitori igbega ti Gomina gbega fun yiyan ti a yan a sinu Ajọ Igbimọ Aṣofin ti *Nigeria* lati ma ṣ'oju gbogbo Igberiko Ilu Ọyọ; o si jẹ nkan iwuri fun ni nigbati Alufa Ẹniọwọ S. J. Gansallo Oloye B.A., fi oyinbo to dọṣọ sọ diẹ ninu igbesi aiye Alagba na; ti o si tun sọ rere ti o wa ninu ki a fun Ilu ti o ba to l'aye lati yọda yiyan enia lọ si Igbimọ Ọba papa nigbati o ba jẹ pe awọn ara Ilu na—bi ti—*Nigeria*—ko rẹhin nipa ṣiṣe Idawo sinu apo iṣura Ilu lori oriṣiriṣi nkan ti Ijọba ba bu owo le ni dida.

Eyi lo ma jẹ akọkọ ti a ori Ẹni-Ọwọ yi ti o sọ ọrọ Ilu ni gbangba oju t'aiye, a si fẹ ki awọn Ẹlẹgbẹ rẹ miran ma ṣai ma tẹle apẹrẹ rere ti Ẹni-ọwọ na fi lelẹ ni ọna yi; irufẹ ero yi lo mu wa sọ Asọye (*Lecture*) kan niwọn ọdun keji sẹhin ti a pe ni *Church and Politics* eyini ni Iba iṣẹ rere ti awọn Alufa le ṣe ni'lu, ti a si tẹ fun tita kakiri nigbana.

Ọrọ ti Ẹni-ọwọ yi sọ wu ẹnikẹni to wa ni'pade na lori lọjọ na; lẹhin eyi ni Ọgbẹni Adeoye ọmọ-ọba ka iwe-iyesi ti a ti pese si'lẹ fun Ẹni-ọla na lede Gẹsi, eyiti Alagba yi si f'esi ti o wọ si lede Gẹsi ati Yoruba bakanna.

Ninu esi rẹ o sọ pe ni ọdun *1872*, o di ọdun kejileladọta nisinsinyi ni on ti ṣe Tiṣa (*Teacher*) eyini ni "Tulẹ" ni Ile-iwe *C.M.S.* ni'lẹyi nibiti a gbe nkọ awọn ọmọ-kunrin igbana ni Ẹko Ọfẹ fun ati ma ṣiṣẹ Olukọni tabi Oniwasu fun awọn Ẹgbẹ *C.M.S.*

O sọ pe nigbana ẹniti o jẹ Ẹgbẹ ati Ọgba on ni Baba wa Arapa-ṣe-fuja, *Bishop* Oluwọlẹ; lẹhin eyi, o sọ pe on ṣiṣẹ gbedegbẹyọ ni Ọgba Ọkọ-Ọba (*Harbour Works*) on si tun ṣiṣẹ fun ọdun mejidilogun l'Eko nibi gẹgẹbi olori awọn "Dẹrẹba" ni Ọgba Ẹlẹwọn, larin eyi ni Ijọba ran on lọ si Ilu Ọba fun ati lọ mọ iṣẹ na siwaju si. O si sọ ohun kan ti o panilẹrin lojiji, pe fun gbogbo ọdun gbọrọ yi, on dupẹ pe on ko joye apẹlẹwọn bi ọbọ lẹkan ri nibẹ.

O si tun sọ pe nigbati on fi iṣẹ Ọba silẹ, ti on si na'wọ gan isinmi to ni Owo-oṣoṣu gbigba ninu, on lọ ṣe Olukọni ni Ile-Iwe Balẹ ni Ibadan nigba aiye Balẹ Apa-npa fun igba diẹ, lẹhin eyi a si fi on jẹ Sẹkitẹri fun iṣẹ Ilu Igboro Ibadan: lẹhinna ni on wa sinmi patapata: ṣugbọn ninu isinmi on o tun wu Ọbangiji Ọba Ogo lati tun fi on ṣe gẹgẹbi kẹtẹkẹtẹ, nì ti awọn ọmọ ẹhin lọ fa fun Jesu nijọkinni; riri ti a si tun ma ri ni pe lairotẹlẹ, o di ọkan ninu awọn Aṣofin Ilu *Nigeria* loni.

Nitotọ, eyi ni iṣẹ Oluwa, o si jẹ ohun iyanu loju wa. Iṣiṣẹ ti ẹnikọkan yio ṣi ninu wa l'aiye yi, ti di mimọ fun Olodumare l'ode Ọrun.

Ẹnyin ara wa, ẹ ko ri ọla Oluwa bayi? Lati ipo olori "Dẹrẹba" titi de Ipo Aṣofin Ilu pẹlu Gomina!!! Ẹkọ nla ni iṣiṣẹ yi jẹ fun ni, o si tubọ fi itumọ owe yi han ni lọtun pe "A ko mọ ibiti ori mb'ẹsẹ re"—"B'a o ku, iṣẹ o tan."

Ko tun si Iwe ti o wọ ju Iwe Bibeli ti awọn Ẹgbẹ na fi ta Ọgbẹni Ọlọla yi lọrẹ lọjọ na lọ mọ. Nigbati o ṣẹ ndi werewere oju alẹ, awọn Ẹgbẹ yi fi ipanu ṣ'ẹrẹkẹ ṣin fun awọn ti a ti pe sibi ariya na, pẹlu ọti tojẹ: eyiti awọn "ọmọ-Eriwo" si ṣ'ọkọ fun daradara.

Ẹnu ko ha ni ya enia lati ri pe gẹgẹbi Ọlọla na ti to ẹni lile lọgọrin ọdun nisinsinyi, kosi irun funfun kan lori rẹ ti a ṣakiyesi; dajudaju ajid'ewe kan to tun ju eyi lọ di ṣaṣa; nibiti a gbe ri ohun bayi ha kọ ni a si ri awọn ẹlomiran ti nwọn koi ni ti to ẹni adọta ọdun ti gbogbo ẹhin (*teeth*) wọn a ti fẹrẹ fi wọn silẹ re itẹ, ti awọn papa a si ti bẹrẹ si di ọkẹgẹ? Kilo mu eyi wa? Awọn miran mọ'iṣin jiję, ṣugbọn nwọn ko mọ iku rẹ yi yan; bẹ ẹniti o ma njẹun gbọn-in-gbọn-in yio ni lati

tikun gbọn-in-gbọn-in ; bi a ti jẹ amọla to, bẹni a o sin wọ laku rẹ to iyẹn ọran iyan.

A ha le ka melomelo ninu awọn ẹlomiran ti nwọn ti fi wiwẹ ọṣẹ awure ba ara wọn ni irun ori jẹ bayi, ti irun ori gbogbo si di funfun bi ori as'ẹfunta.

A ko ma sọ ti awọn oni ewu idile o.

Diẹ ninu awọn ọmọ ẹgbẹ ti a ri loke lọjọ na lẹhin Alufa S. J. Gansallo leyi :— Alufa S. A. Pearse, awọn Ọgbẹni T. I. Kester, E S. Kester, A. Phillips, Dan. Pratt, H. A. Babalọla, Prince Adeoye, L. Randlle ati awọn jakanjakan miran.

Şugbọn o dunni pe a ko ri ọkan ninu awọn Iyẹ-afin wa, awọn "ẹlẹyinju'ẹgẹ" obinrin Ẹgbẹ na ki nwọn ta bi oşumare loke lapakan ibiti awọn Bọkinni yi joko si; iyan awọn "Gbàdà-nibi" wa wọnyi ko ma şe ko kere o, a sọ eyi lọwọkan.

Ẹ ku aşeyẹ ọjọ ẹ n yi n ọ m ọ Alafin, Ajalọrun a gbe nyin karikari. Aşẹ

---

## *Open Letters.*

TO CELEBRITIES, NOTORITIES, ETC., IN DIFFERENT WALKS OF LIFE.

**No. 47.**

To

HIS EXCELLENCY
SIR DONALD CAMERON K.B.E., C.M.G.
*Acting Governor, of Nigeria,*
Lagos.

Your Excellency,

It is to me no little joy to read the news flashed through *Reuter's* only a week ago with particular reference to your preferment to the Governorship of Tangayika, by command of His Majesty the King.

Would it seem paradoxical to say that no sooner the news was spread to the four corners of Lagos, or of Nigeria for the matter of that, than the whole community was plunged into mourning, so to speak ? Not because of our displeasure in Your Excellency's well-merited promotion in His Majesty's Service, but because of our being about to lose one who to us, has been *our Father and Frien l*, in season and out of season, through thick and thin these many years; when one recalls to mind, Your Excellency's tactful acts in more ways than one, it is little wonder to see that you have thus become a *persona grata* to our people, both high and low, rich and poor, learned and unlearned.

Again, it is no fulsome adulation to remark that you are to us Africans of this great Dependency, a *Rara Avis*, owing to your proverbial shrewdness, coupled with that high sense of duty, and a large heart, for which Your Excellency is well-known and which has made you, Sir, a *Sui Generis* in the usual discharge of your onerous duties to all classes alike regardless of colour.

But as the best of friends must part, even for a while, as Your Excellency hopes to do, shortly for the scene of your future labours, it is my *earnest and fervent* wish as well as the wish of the teeming millions of this Tropical Dependency that it may not be many years hence, when it will please His Most Gracious Majesty The King to return you again to these shores as the Governor and Commander-in-Chief thereof. So Mote it be !!!

Meanwhile, please accept my hearty congratulations, and may your successor in Office be one on whom "the mantle of Elijah will eventually fall."

Adieu, Your Excellency.!!!

EKO AKETE.

---

## AT'ARÉDÈ, AT'ARÉDÉ, K'A GBỌ TI JESU RE MO MỌ!

[*Lati ọwọ* ATARI AJANAKU.]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji,

Li oju ọpọlọpọ Şọşi awọn Kiriyo Eko ati ti ilu miran, ọkunrin tabi obirin ti o ba gbe arede tabi iyawo, o pegede ; ọjọkijọ-ti oluwarẹ na ba si ku, ti o ba kan ilẹkun ọrun rere ko, ko, ko, bi St. Peter, ẹniti a gbọ wipe o wa li oju ọna ba bere wipe, Iwọ tani yẹn ? Ti o ba dahun wipe, on Lagbaja ni, bi o ba si tun bi i lere wipe, iru enia wo ni iwọ jẹ li aiye ? Ti oluwarẹ ba dahun wipe, igba kan şoşo pere ni on jale, ti Ijọba si fi on si ẹwọn ọdun meje, lẹhinna, on ta tẹtẹ, on nmu ọti, ti on ba si purọ mọ ẹnikan, Ọlọrun nikan ni o le yọ oluwarẹ kuro ninu wahala na, on si fẹran ọkunrin pupọ. Ti St. Peter ba si tun bere lọwọ rẹ wipe, Iwọ ha gbe arede bi ? Ti obirin na ba sa ti le f'esi bayi wipe, on gbe arede, Mrs. Lagbaja ni on, on si gba oruka : werewere ni a o şi ilẹkun fun u, ti yio wọ ile, ti yio si joko ti awọn aşiwaju rẹ nibẹ, ti nwọn o si ma jumọ kọ orin :—

"Ire t'a su ni Eden,
Ni'gbeyawo kini ;
Ibukun t'a bukun wọn,
O wa sibẹsibẹ."

Şugbọn, ẹniti o ba sọ fun St. Peter wipe, on ko wọ ẹwọn ri, on ko mọ ọti mu, on ko purọ mọ ẹnikeji on ri, on ko nta tẹtẹ, on nşe itọrẹ anu fun talaka gẹgẹ bi agbara on ti mọ, on bẹru Ọlọrun, on ko si pe orukọ Rẹ lasan ri, on npa ofin mẹwa mọ. St. Peter yio gb'oju mọ ọ wipe, Itan ni

gbogbo 'yẹn; o gbe arede tabi o ko gbe? Ti o ba gba Oruka, ki o wọ ile, bi bẹ kọ, lọ si ọdọ *Lucifer* li Ọrun Apadi, ibẹ ni ile awọn Madam ati Daddy ti ko gbe iyawo.

A ha fi Kristi kọ nyin bẹ, ẹnyin onikekere Igbagbọ? Onigbagbọ-ki-onigbagbọ ti o nro iru ero bayi, ntan ara rẹ jẹ ni; a ko ngbe iyawo li ọrun, bẹni a ko si nfi nwọn fun-ni ni iyawo nibẹ. Igbeyawo, ohun aiye ni: olukuluku orilẹ-ede li o si ni aṣa tirẹ!

Aye ko si fun wa li ọsẹ yi lati to eto oniruru igbeyawo orilẹ-ede gbogbo li ẹsẹsẹ. (iyẹn ti a ba tilẹ le ṣe bẹ,) ṣugbọn a le sọ niba ṣoki wipe, iru igbeyawo ti ọpọlọpọ Ṣọṣi gba kan'ri nisisiyi bi eṣinṣin gba igba ọti jẹ awokọ, tabi itunṣe lori isin igbeyawo awọn abọriṣa ilu Romu—ilu ti o la awọn Oyinbo Gẹsi l'oju, ti o si ran Bishop Enia Dudu kan, Augustine, ẹbi Odudua, ẹniti o pada di Archbishop lẹhinna lọ ni A.D. 597, (ẹdẹgbeje ọdun, o le mẹtadi-lọgbọn nisisiyi) lati lọ wasu Ihin-rere fun awọn Oyinbo, lẹhinna ni nwọn bẹrẹ si di Onigbagbọ ni eni-tere, eji-tere, ki awọn papa to di ẹniti o nni Deacon, Archdeacon, Bishop, Archbishop li arin wọn loni, ti nwọn ko si fẹ lati fi Enia Dudu jẹ oye Bishop kikun mọ, bikoṣe oye pẹ-pẹ-pẹ miran.

Nigbati awọn Oyinbo kọkọ gba ọjẹgẹ igbeyawo olobirin kan, yala o rọ wọn lọrun, tabi o ni wọn l'ara ni o, awa ko mọ. Ṣugbọn, gẹgẹ bi iṣẹ, oṣi ati airikanṣekan ti pọ to ni ilu wọn, ati bi iya ile ti jẹ wọn to, ti o ṣe wipe ipa ati inira nla ni ẹnikọkan ninu ọkẹ aimoye enia fi le ri owo haya oju'le kanṣoṣo fun ara rẹ lati gbe, a ko le ṣe aiki ẹniti o ba jaja tiraka-tiraka gbe obirin kan ni iyawo wipe, o ku inawo!

Aṣọ-ẹbi, kil'o njẹ bẹ? Owo ti awa Enia Dudu fi ngbe iyawo kan, Oyinbo le fi gbe mẹfa. Sibẹsibẹ, a ko mọ chun ti a nṣe. Iya ti ọkọ alarede miran fi njẹ aya rẹ ko kere; ọpọlọpọ alarede ha kọ ni obirin ita ko jẹ ki o kia (*care*) fun t. ile mọ, li aika ogunlọgọ awọn obirin ti ale (*Sweet-heart*) ọkọ wọn npa owe mọ li ọja Ereko ati Ita Faji?

Ki nto ma jẹ faji ọrọ nṣo, mo fẹ ki o ye gbogbo enia gbangba wipe, nko kẹgan arede, nko wipe o dara lati ni obirin pupọ ju ẹyọ kanṣoṣo lọ, ohun ti mo ngbidanwo lati sọ ni wipe, sẹria ti o sọ Oyinbo di olobirin kan ninu ibọriṣa wọn, ki ẹsin Igbagbọ to de arin wọn, ati wipe, nitorina, a nṣe ete l'ọṣọ ni nigbakugba ti a ba npe e ni ti Onigbagbọ tabi *Christian Marriage*.

Nko jiyan wipe a ko le tumọ igbeyawo "*For better for worse*" ko ba diẹ mu ninu ọrọ Testament titun, ṣugbọn mo sọ ọ, mo tun sọ ọ wipe, Oyinbo ti nṣe "*For better for worse*" li arin ara wọn ki nwọn to mọ rara wipe Iwe kan tilẹ wa li aiye ti o njẹ *Testament* lailai, tabi *Testament* titun.

Nipa ọrọ obirin, awọn ti a le pe ni janduku ti ko ni ẹbun imaraduro li o kun inu *Testament* lailai tẹtẹ, awọn ẹni bi Dafidi ati Solomon ọmọ rẹ ti o ni ẹdẹgbẹrin aya ati ọdunrun ale, (*Seven hundred wives and three hundred concubines!*) ṣugbọn ni ikẹhin, o ka gbogbo wọn si asan ati imulẹmofo. Abrahamu papa ti a sọ fun wa wipe on ni apẹrẹ igbagbọ ati ọrẹ Ọlọrun, ko duro ti Sarah nikan!

Ko da ni loju wipe *Testament* titun yọda ikobirinjọ, ani, St. Paul tilẹ fẹran *Bachelor* tabi Apọn totọ-totọ, ti ko ni obirin rara ju ẹniti o ni aya kanṣoṣo lọ, l'aibikita, boya, fun aṣẹ Ọlọrun ti o sọ wipe, "Ki a ma bi si i, ki a si ma rẹ si i."

Ipinnu olobirin kan yi ba aṣa Oyinbo, papa ti Gẹsi mu; aṣa wọn, ani, li akoko ti nwọn tilẹ nbọ igi, bọ ọpẹ. Nitorina, nigbati nwọn di O[illegible] igbagbọ tan, nwọn fun ika mọ ọ girigiri, nwọn si fi ofin gbe e l'ẹsẹ.

Dajudaju, ati l'aisi ani-ani, ibaṣe wi[illegible]e ikobirinjọ ni aṣa ilu wọn tẹlẹ ni, ki Enia Dudu jẹ olobirin kan, Ọba Ilu Oyinbo miran iba ṣe ju Solomon lọ. Gẹgẹ bi apẹrẹ, nigbati Jesu kọ wa ninu Testament titun wipe, "Bi ẹnikan ba gba ọ li eti ọtun, ki o yi ti osi si i," ti ofin Oyinbo si wipe, "Bi ẹnikan gba ọ li eti ọtun, ki o pe e l'ẹjọ si Kọtu:" ewo ni Oyinbo tẹle ninu mejeji, ofin tiwọn ni, tabi ti Jesu?

Awọn Lọya tabi Amofin ti Jesu fi bu ninu *Testament* titun ha kọ ni awọn enia pataki julọ ni Ilu Oyinbo l'oni?

Nigbati Iwe-adura ti Ṣọṣi kilọ wipe ẹnikẹni ko gbọdọ gbe aburo tabi ẹgbọn aya rẹ ti o ku ni iyawo, Oyinbo ko ha ṣe ofin wipe, enia le gbe e ni a-gbe-dara. Nigbati Jesu ni ki a ma ṣe itọrẹanu fun talaka ati alaini, Alumọngeri tabi Onibara kan ha gbọdọ tọrọ jẹ ni Ilu Oyinbo, ki o ma di ẹti si i l'ọrun?

Pupọ bẹ ni a le ka ti o jẹ wipe ibikibi ti ofin tabi aṣa Oyinbo ba yatọ si ofin Bibeli, ofin Oyinbo ni nwọn njẹ ki o b'ori; nitorina, nigbakigba ti a ba ri ofin tabi aṣa Ilu Oyinbo ti o ba ti *Testament* lailai tabi titun mu, o ṣẹṣi bọ si i ni, ki a ma si ṣe ro wipe, ofin Onigbagbọ ni.

Ofin arede obirin kan yatọ patapata si *Tastament* lailai, ti o ba si ba *Tastament* titun mu, o ṣẹṣi ni, iyẹn ko pe e ni igbeyawo Onigbagbọ rara, aṣa Ilu Oyinbo lasan ni.

Ohun ti o dara pupọ fun ọkunrin ni lati fẹ obirin kanṣoṣo, ki o si ya ọna agbere silẹ. Itẹlọrun ti alarede iyawo ẹlomiran nfun u ni ile pọ tobẹ gẹ, ti ọkọ rẹ ko tilẹ jẹ fẹ ehin si obirin miran li ode, de ipo ti o ma ṣ'ẹju si i. Ṣugbọn eṣu beleke ni aya, eṣu beleke ni ọkọ alarede miran.

**Ni Ilu Oyinbo papa nkọ, omi igbin ko tu igbin, ẹni he ni on he ẹrọ. Ojojumọ, ọsọsẹ ha kọ ni**

t'ọkọ-t'aya ngbe ara wọn ni iyawo l'oni, ti nwọn si ngba Iwe-ikọsilẹ ni Kõtu l'ọla; igbagbogbo ha kọ ni awọn Mrs. Oloruka nkọ iwe nibẹ si ọkọ wọn wipe ki o jọwọ pe wọn li ẹjọ ikọsilẹ, nitori awọn ti da ilẹ li aşiri pẹlu ọkunrin miran, ẹniti awọn fẹran pupọ ju ọkọ wọn lọ, ati wipe, awọn si ti wọ ẹwu Buba B'o-n-fo, lati ba ale (*Sweet-heart*) wọn na lọ si ibikibi l'abẹ Ọrun?

Nigbati ọrọ ba di kara-n-gida bayi, kini Afa Şọşi ti o gbe iyawo fun wọn le şe; işẹ di işẹ Loya, ọrọ di ti Kõtu; Onidajọ Kõtu nikan ni o le fun wọn ni Iwe-ikọsilẹ, bẹni Afa-ti wipe, "Awọn ẹniti Ọlọrun ba ti so ş'ọkan, ki ẹnikẹni maşe ya wọn." Ati li ainani ikilọ ati ofin *Testament* titun wipe, "Ẹnikẹni ti o ba gbe obirin ti a kọ silẹ ni iyawo, o şe panşaga," igba pupọ ha kọ ni ẹnikan tun ngbe obirin ti ẹnikeji rẹ kọ silẹ ni iyawo gẹgẹ bi ofin Ilu Gẹsi ti o l'odi si ti Bibeli ti Şọşi si nfun awọn mejeji ni *Sacrament* tabi Onjẹ-alẹ Oluwa jẹ lẹhin na.

Eyi tun jẹri si ọrọ ti a sọ siwaju pe nibikibi ti ofin tabi aşa ilu Oyibo ba yatọ si ti Bibeli, ti ilu wọn ni nwọn ntẹle, ati pe nitorina, arede ti a ngbe, aşa ilu Oyinbo ni, ko nşe igbeyawo ti Onigbagbọ.

Ju bẹ lọ, lakoko kan ri, o lodi patapata si ofin Oyinbo fun ara ilu Jew lati gbe Onigbagbọ tabi Christian ni iyawo, ẹniti o ba si ru ofin na, ina hẹhẹ ni nwọn nda sun nwọn laye, titi nwọn a fi jona di eru patapata, bẹ gẹgẹ si ni ara *England* ko gbọdọ gbe ara ilu *Wales* ni iyawo. Ofin wọnyi ti yipada diẹ nisisiyi, şugbọn, sibẹsibẹ titi di oni oloni, ọmọ ọba ilu Gẹsi to ba gbe obinrin to nsin ẹsin "aguda" (*Roman Catholic*) ni iyawo şẹ si ofin ilu, ko si le jọba bi oye ọba tilẹ kan a, nigbati baba rẹ ba wọ àjà.

Bi Oyibo *German* kan gbe obinrin Oyibo Gẹsi ni iyawo ni ilu Gẹsi bi *England* tabi ibomiran, ayaşebi nwọn ba şe isin igbeyawo na ni ilu Gẹsi gẹgẹ bi nwọn ti nşe gan ni *Germany*, bi bẹkọ, ijọkijọ ti ọkọnrin German ọkọ iyawo Gẹsi yi ba de *Germany* ilu rẹ, ko si ofin kofin to le di i lọwọ lati gbe iyawo miran lai kọ obinrin ti o ti gbe ni iyawo ni ilu Gẹsi silẹ.

Bi Oyibo Gẹsi onigbagbọ ọkọnrin si gbe onigbagbọ obinrin Faranse ni iyawo ni ilu Faranse, igbeyawo na ko murọ mọ bi nwọn ba de ilu Gẹsi, ayaşebi a şe eto igbeyawo na gẹgẹ bi ti Gẹsi ilu ọkọ, bi o ti lẹ ti jẹ pe obinrin Faranse ni a gbe ni iyawo ni ilu Franse.

Ko yẹ ki eyi ri bẹ rara, ti o ba şe pe igbeyawo onigbagbọ lasan ni, laisi ọrọ ofin tabi àşà ilu nibẹ. Ni ilẹ yi, onigbagbọ ọmọ Eko le gbe onigbagbọ obinrin Adelamu ni iyawo, Ijẹbu le gbe Ijẹşa, ara Ogbomọşọ le gbe Tapa, Ẹgba le gbe Işẹkiri, ara Ibadan le gbe Hausa ni iyawo, Isobo le gbe obinrin Oyibo Gẹsi papa ni iyawo. Ko şe pe nitori gbogbo wọn jẹ onigbagbọ ni eyi fi le ri bẹ, bikoşe pe gbogbo wọn lo wa labẹ asia ati abo Ijọba Gẹsi. Nigbati a ndi pali (*Collar*) mọ ọrun pẹlu akisa (*Tie*) bi ologbo, ti a nwọ şokoto fàtófàtó, ti bata yọ kókó (*Corn*) si wa l' ẹsẹ, Oyibo ha kọ ni a nfi ara we?

Gẹgẹ bi aşa igbeyawo ilu Gẹsi yi, t' ọkọ t' aya le gbe iyawo ni Kotu lai tilẹ de Şọşi rara, akọwe Kotu (*Registrar*) to ma gbe e fun wọn si le jẹ Imale tabi Keferi. Iya fẹ, iya kọ, Baba fẹ, baba kọ, ko di Oyibo lọwọ rara lati gbe iyawo, iwa ọdaju buruku ti Oyibo ko wọ ilu wa to si njẹ ọpọlọpọ awọn ọmọ wa ni 'ya nile ọkọ nisisiyi.

Gẹrẹ ti Oyibo ba ti gbe iyawo tan, ko mọ iya tabi baba mọ, afi on pẹlu aya rẹ nikanşoso, ti Ọlọrun ba si jajà yọda ọmọ kan tabi meji fun wọn, ofin ilu wọn ko tun bikita fun iya tabi baba awọn mejeji mọ.

A ngbọ Famili, Famili (*family*,) ọkọ aya ati ọmọ nikan ni ofin Oyibo mọ ti nwọn si npe ni "*Family*." Baba ko si ninu *family*, ti wọn, iya ko si nibẹ; ko si ẹgbọn, ko si aburo. Eyi lo jẹ ki ọkọ nikan le jẹ oguu gbogbo ohun ini aya tèfètèfè, ki aya si le jẹ ti ọkọ, ẹnikẹni ninu awọn mejeji iba fi akuşẹ arugbo iya tabi baba silẹ l'aiye, ka ma şẹşẹ sọ ti aburo tabi ẹbi miran. A ha le ka iye ijẹkujẹ ogún ologún bayi ti awọn alarede Enia Dudu papa ti jẹ ni Eko yi gẹgẹ bi ofin Oyibo, to ba si jẹ pe ofin Bibeli ni eyi, ki awọn Afa jẹ ki a gbọ.

Nipa ọrọ arede yi, aşa tabi adiẹ olopipi to ju Oyibo lọ ko si; bi ọkọ ko pe aya ni õrun fun ijọ melo kan, eyiti itiju ko njẹ ki awọn obirin wa le ro iru ẹjọ bayi si ita fun eti meji gbọ, ẹjọ ni Oyibo yio pe ọkọ rẹ si Kotu ti yio si haya Lọya ti ndi, ti yio si sọ fun onidajọ nigbangba Kotu loju gbogbo enia pe ọkọ on ko fi ọwọ kan on lati ijọ mẹta wa, Onidajọ yio si paşẹ pe ki ọkọ bẹrẹsi lọ sun ti aya rẹ, ko si san owo irin ẹsẹ. Bi ọkọ ba tun kọ lati sunmọ iyawo rẹ lẹhin aşẹ yi, bi Kotu ba fẹ o le jẹ ẹ ni iyà fun "*Contempt of Court*" tabi iwa ẹgan si Kotu, bi ori rẹ ba si ta ko o, Onidajọ le fi si ẹwọn nitoripe ko sun mó iyawo rẹ.

Bi o si şe aya ni ko fi aye silẹ fun ọkọ, bẹ gẹgẹ ni ọkọ yio pe e lẹjọ, bi onidajọ ba si fi asẹ si i, ti nwọn ba pada de ile, ti obinrin kọ sibẹsibẹ, to si sọ fun ọkọ rẹ gbangba pe on ti ri Baba Isalẹ to ntẹ on ni bafin ni bokẹlẹ, to si ntẹ on lọrun nigbakugba, ohun ti ọkọ le şe ni pe ki o pe aya rẹ l'ẹjọ ikọsilẹ ati gẹgẹ bi ofin arede Gẹsi yi ti nwọn npe fun wa ni iyawo onigbagbọ, ọkọ lo ni lati haya Lọya fun 'ra rẹ, ki o si tun fi owo apo rẹ haya Lọya fun obirin, o si ni iye owo tiantian ti ọkọ ni lati san ni asantẹlẹ si Kotu, ninu eyiti aya rẹ yio ma fi jẹun, fi da 'şọ ati lilo fun ohunkohun to ba fẹ titi ẹjọ yio fi pari, nwọn si le ro ẹjọ na siwaju, sẹhin, ki ọkọ tun jẹbi le e lori, papa to ba jẹ ọkọ to ni ọrẹ obinrin miran s' ode laşiri. Irufẹ ofin bayi lo jẹ ki ọpọlọpọ panşaga alarede aya

miran nilẹ yi di egungun ẹja ha bàle wọn lọrun—iru ofin bayi lo jẹ ki "*Best man*" tabi igbakeji ọkọ iyawo tun le pada di ọkọ obirin ti o ṣe *Best man* fun ọkọ rẹ nijọ iyawo, ti obinrin na nbimọ fun un, ṣugbọn ti ẹjọ ọkọ ko wọ Kotu nitoripe on papa ni ọmọ l' ode. Bi ọkọ tilẹ bi ọmọ sode, iyẹn lo ha wipe "*Best man*" le jẹ iyawo rẹ ni ajẹgun ti oriṣa njẹ igbin? Ani, iru ofin arede Oyinbo yi lo jẹ ki ọpọlọpọ onigbagbọ di agabagebe nitori ati ri aye jẹ *Sacrament* tabi Onjẹ-alẹ Oluwa ni Ṣọṣi, ti ẹlomiran ninu wọn, ninu agabagebe rẹ ṣe abosi titi o fi sin ọmọ rẹ obinrin ni iyawo fun ọkọ ni adugbo kẹdọgbọn, lai sọ ohunkohun fun "*my dear*" rẹ to wa nilẹ.

Gẹgẹ bi ofin arede Oyinbo, ọkọ le kọ silẹ nitori agbere, ṣugbọn aya ko le kọ ọkọ silẹ nitori agbere nikanṣoṣo, ṣugbọn o ṣoro fun ọkọ ti iyawo rẹ wa ni Olowogbowo, ti ale rẹ wa ni ita Balogun, tabi eyiti o bi ọmọ sode lati kọ alarede rẹ silẹ bi iyawo na tilẹ nhu iwakiwa, bi nwọn ba si pe ara wọn lẹjọ, eyiti Kotu le ṣe ni pe ko fun wọn ni ni iwe ipinya ti a npe ni "*Judicial Separation,*" lẹhinna, olukuluku wọn le ma lọ ni ọtọtọ, ọkọ yio ma san owo ti a npe ni *Alimony* fun iyawo rẹ loṣoṣu, oṣu to ba se, Kotu le ta ẹru ọkọ na ni gbanjo, tabi ko gbe on papa ju si ẹwọn 'gbese.

Nwọn le wa ni ọtọtọ bayi fun ogun ọdun lai sun mọ ara wọn, ṣugbọn pẹlu gbogbo ipinya na, bi ẹnikan ninu won ṣeṣi lọ gbe ẹlomiran niyawo, o gbe Jombo—ẹwọn idi rẹ yio gun de Saro fun ẹṣẹ ti a npe ni "*Bigamy.*"

(Koi ti pari. Iyoku di ọsẹ to nbọ lagbara Baba, nitori a fẹ ki gbogbo alarede mọ diẹ ninu ofin ajaga ti a nti bọ nwọn lọrun, papa awọn ara oke to ṣẹṣẹ ngbagbọ. A ko wipe ki ẹ maṣe gbe iyawo o.)

Emi ni tiuyin nitotọ,

ATARI AJANAKU

---

IROHIN KUKURU NIPA ẸJỌ ILE-ẸJỌ GANRAN, TI O BẸRẸ NI OJO TUESDAY, OJỌ KARUN OṢU YI. ỌLỌLA FREDERICK ALAN VAN-DER MEULEN, ADELE ADAJỌ AGBA LI O JOKO.

---

Ile-ẹjọ to bẹrẹ yi gẹgẹ bi iwe awọn Ọdaran ta nu ẹjọ wọn wa siwaju, ẹjọ meje ni gbogbo eyiti o wa ninu iwe na.

Ekini ni, ẹjọ Bogobiri ẹniti nwọn fi sun fun ẹṣẹ ọsọlẹ nipa wiwọ ile Mọmọ Bogobiri, ti o si ji i ni woro to jẹ oniye pọnwun mẹtadi-lọgọta ati owo ẹgbẹta pọnwun o din mẹtadiladọta, ẹjọ yi wa ninu Ile-ẹjo ti oṣu may 1924, ṣugbọn ki la ma ri o ku ọla ka wi'jọ ẹkun pa ẹlẹri—gẹgẹ bi ẹ ti ngbọ orukọ Ọgbẹni Gambari to ku l'Oko-awo; ti orukọ rẹ njẹ Mọmọ Bogobiri; ni Bogobiri oloruko rẹ ja l'ole,—ki la tun ma ri a gbọ pe Bogobiri yi sa lọ—Adajọ pe awọn Ọgbẹni meji to duro fun, fun Ọgọgọrun pọnwun fun ẹnikankan ko la san owo iduro yi fun Ijọba kiakia wara wara nṣe ṣa, ti nwọn ko ba san Ijọba a lẹ iwe ipa mọ ile olukuluku wọn, ọkan ninu awọn oniduro yi orukọ rẹ a ma jẹ Gbadamọsi Mọgaji *74, Idoluwo Street, Lagos*, ekeji a ma jẹ Tijani Ekugbe 29 Isalẹ-Agbẹdẹ, ki Ọba ko ṣọ ni ninu agbako nla.

Ekeji ni Joseph Ọlọrunfẹmi ẹniti Ijọba ki l'orun mọlẹ ni Ijofin l'apa Ilaro fun jiji *(6 Raleigh Bicycle and 1 Ringer Cycle)* Kẹkẹ Ologere meje ṣugbọn ọkunrin yi ni on ko jẹbi, ṣugbọn awọn agbagba mejila ni o jẹbi, ibẹ ni Agbẹjọro Ọba ranṣẹ pe Ọgbẹni Ọlọwa ti o nṣiṣẹ ni Kotu Ọlọpa nibi lati wa sọrọ nipa gẹgẹ bi Ọdaran yi ti wọ ẹwọn ni Ado Ekiti o si sọ niba ṣoki pe Ọdaran yi orukọ rẹ nigbana ni Joseph Awopẹtu o ji (*Bicycle*) Kẹkẹ ologere ti ẹni owọ Alufa Dale ni 1914 nigbati on nṣiṣẹ ni Ile-ẹjọ ni ọhun. Adajọ si fi si ẹwọn oṣu mejidilogun nigbana—Ọlọla Adajọ Vander Meulen ni iwọ Ọdaran Kẹkẹ ṣa lo nṣe ẹ si nigbagbogbo; nitorina wa lọ si ẹwọn ọdun marun pẹlu iṣẹ aṣe-lagun ati ẹgba mejila—(*5 years hard labour and 12 lashes.*)

Ẹkẹta ni Ọgbẹni Israel George Macauley ti nọmba 102 ita Tokunbọ ni Eko ti Ijọba ragabu rẹ fun ẹṣẹ ọsọlẹ ti o fọ ile Ọgbẹni Thomas John Marshall ti o si ja'le, ẹsun kini ni fifọ'le ti o si ja'le, ẹsun keji ni wipe o kọ orukọ T. J. Marshall sinu iwe *Bank* lati gba pọnwun mẹwa, ẹsun kẹta ni pe; o fi eru ṣe'we lati gba owo pọnwun mẹwa, ẹsun kẹrin, ni pe o kọ orukọ T. J. Marshall sinu Iwe *Bank* lati gba pọnwun mẹsan, ẹsun karun, wipe o fi eru ṣe'we lati gba pọnwun mẹwa, ẹsun kẹfa, ni pe o ji pọnwun mẹwa, ẹsun keje, ni pe o ji pọnwun mẹsan-l'ori gbogbo rẹ, o ni on ko jẹbi nigbati awọn *Jury* wa'di ọrọ rẹ nwọn ri pe o jẹbi ẹsun wọnyi, Ekini, Ekeji, Ẹkẹta ati Ẹkẹfa—lẹhinna Adajọ bere to ba ni ọrọ sọ, o ni ọrẹ on ni Ọgbẹni Marshall fun nkan ọdun meji ọhun ati wipe on nṣiṣẹ agbẹdẹ (*Mechanic*) ni ọkọ Okun, on ti lọ si ilu Oyinbo oni iye igba; ki Adajọ ko jọwọ ko fi oju anu wo on—nitori on ko wọ ẹwọn ri.

Adajọ ni on mọ dajudaju pe ọrẹ ni iwọ pẹlu Ọgbẹni Marshall, ati pe ko si tọ si ọ lati ṣe ni ofun bayi, to fi apakan ile rẹ silẹ fun ọ lati ma lo nigbati o nlọ si Ibadan, ṣugbọn o sọ wipe o ko wọ Ẹwọn ri, nitorina on a fi ọ sẹwọn ọdun mẹta pẹlu iṣẹ aṣe lagun.—

(*Koi ti pari.*) GBỌBANIYI

---

### A CORRECTION

The date of the death of the wife of our respected townsman Mr. R O Staveley of 44, Campbell Street, Lagos is Sunday the 20th *ultimo* and not the 28th as inadvertently published in our last issue.—Ed.—E.A.

**J. C. VAUGHAN**

Ti Ile-Oja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Oja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ nina awọn onişowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.


## Ero ya wa ra


ADEBOYE ŞOLANKE Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikanọkọ, Iṣọ lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ile-ọja rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ.

On si ni aşoju awọn ẹgbẹ Oyinbo onişowo to njẹ Arnold Whitehead Ltd. to wa n Manchester (Ni'lu Oyinbo) to si nranşẹ orişi-rişi ọja fun-ni lat'ọdọ wọn ni Eko ati agbegbe rẹ. Lọ ş'abere ẹhin ọrọ nipa owo yi lọwọ rẹ ni Şabu rẹ tabi ki o kọwe ranşẹ si ki o fi şọwọ sinu apoti ikọwe si t'Ọbẹ P.O. Box No. 796, Eko, Nigeria.


ŞEUN, ALAGOGO AJILU GBỌNUN, GBỌNUN.

Ọrẹ wa Ọgbẹni S. A. Yewande onişẹ agogo titun şe nta "Eko Akete" ni ile rẹ Ẹnuyami ni 101 Patey Street, Ebute-Mẹta. Ẹnyin ara Ebute-Mẹta, ẹ maşe jafara ati lọ ra ti nyin nibẹ ni gbigbona lẹlifẹli ni Satide Satide.


**Cable Address:—**
"Steinafrik" HAMBURG
E. H. STEIN & Co.
HAMBURG, Neuerwall 16/18,
Hildebrandhaus.
*AFRICAN MERCHANTS.*

*ALL INDENTS EXECUTED.*
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos :—
**Mr. Karimu Kotun**
3, DOSUNMU STREET.

**Ruby Plates! Ruby Plates!! Ruby Plates!!!**

BOON TO GOLDSMITHS

*Just arrived.*

Call at once and make your choice from :—
DURO THOMAS,
55, Massey Street, Lagos.



ŞABU AJIŞEFINNI.

Gbakan-nşubu orişirişi Ọti *Beer* to jire wa fun tita ni Şabu Ibukun Oluwa, Şabu ti Mrs. E. Labinjọ ni No. 28, *Luther Street*, leti Mọşalaşi Olosun. Sarotu kekeke (*Cigarettes*) si nbẹ nibẹ bi tẹdi. Awọn *Lozenges* ati *Peppermint* lila, papa lakoko oworẹ yi ko şe fọworọ şehin. Gbogbo awọn ọja Şabu na lo nşẹju si ni, pe kami, kami, kami.

Ọrẹ, sure tete lọ ra tirẹ nibẹ.

Kai! afara ni'ja Ẹkun.

# A. Kessler,

7, Labinjo Lane,

Williams Street,

**P.O. Box 459**



THE

# Pilsener Beer

*Lion Brand*

*Light & Sparkling*

**Per Case**

**34s.**



## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*



## Aworan Alarabara.

A ni Aworan oniruru fun tita lati fi şe ile li ọşọ. A ni ti itẹ oku Jesu, ti igbati a da a li ẹbi iku, ti Onjẹ-alẹ ikẹhin. A ni ti Adam ati Efa, ti işẹdalẹ aiye, ti Nebuchadenezar nigbati o wa ninu ọla rẹ, ati nigbati o di ẹranko; ti obirin ti o fi ọwọ mu ejo, ati ti Oba Tatambulu.

A ni ewe Taba fun kika ta, Ọşẹ Olowo—agaga; Iyọ-iyọ mbẹ lọwọ wa fun tita bi wọbu, bi o ba fẹ ẹ ni *ipu* a le ta a fun o, Işana Alapoti fun tita, ko si bi a ti nşe wọn. Orişirişi ọja lo wa lọwọ wa, iwọ ko le ba wa şowo ko ma jere tirẹ, nitori owo pọku ni a nta wọn. Owo ọja wa rẹja rekoja ala. Bi o ba wa si ile-ọja wa "Ka mi, ka mi, ka mi" ni gbogbo wọn, bi o ba fẹ ja irọ wa, rin wa si ile ọja wa.

Iye owo wọn:—3d, 4d, 5d, 6d, fun ọkọkan; 2/6d, 3/-, 4/-, 5/6d fun mejila.

Ibikibi ti o ba ngbe ni *Nigeria* tabi ẹhin okun kọwe şowọ yala ni ede Gẹsi tabi ti Yoruba si:—

E. O. AMBE & BROS,
38, Moloney Bridge Street, Lagos,
*(Lẹgbẹ awọn Onişowo A. J. Tangalakis),*
Idumagbo, Eko.



## Ile Ita Egbogi ti Macaulay,

88, BROAD STREET.

Wabiwọsi orişirişi Egbogi lo şeşẹ de fun wa ni tita: awọn bi:—ogun Egbo orişirişi, ogun Ẹda, ogun arun aşiri, ogun Arẹmọ, ogun Onigbameji, ogun Aran orişirişi, ogun Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko le mã to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si jẹ bi idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wọnyi wo nibi ti a gbe nta wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGAAT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.